IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 759 SATURDAY AUGUST 1, 1964 (2D)

## Ijọba Ti Gbe Oloye Enahoro lọ si Ọgba Ẹwọn Kirikiri

EKO-: Ni owurọ Ọjọ'Bọ ti ise Ọgbọnjọ Osu keje Ọdun yi ni ijọba gbe igba keji Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Anihony Enahoro kuro l'ọgba ẹwọn Broad street l'Eko ti nwọn si gbe lọ si Ọgba ẹwọn kiriki ni Apapa.

Irohin fi ye wa pe ni owuro ọjọ'Bọ ti ise ọgbọnjọ Oṣu keje Ọdun yi ni mọto si de ọgba ẹwọn ti Broad street ti nwọn si ṣe eto lati gba Oloye Enahoro kuro l'ọgba ẹwọn na lọ si kirikiri ni Apapa.

Nigbati nwọn sẹ eto na tan ni nwọn ni ki oloye Enahoro wọ inu mọto ti ọgba ẹwọn na lati gbe e lọ si ọgba ẹwọn ni kirikiri ni owuro kutukutu ọjọ na lati lo duro de asiko ẹbẹ idajọ rẹ ni ile ẹjọ giga julọ ti ile Naijiria.

Agbẹjọro fun oloye Enahoro Ọgbẹni Abraham Adesanya fi ye oniwe irohin wa pe on ti gbọ pe nwọn yio gbe oloye Enahoro kuro lọgba ẹwọn ti Broab stree sugbọn on ko mọ ọgba ẹwọn ti nwọn yio gbe e lọ.

Ọgbẹni Adesanya so pe on ko mọ idi rẹ ti nwọn ṣẹ fẹ gbe Oloye Enahoro kuro lọgba ẹwọn ti Broad Steet rara

# IYA AFIN AWOLỌWỌ LỌ ṢE IBẸWO AWOLỌWỌ

KALABA:- Ni ọjọ'Bọ ti iṣe Ọgbọnjọ Oṣu keje Odun yi ni Iya-Afin Oloye H I.D Awolọwọ iyawo Olori egbẹ Afẹnifẹre eniti ile ẹjọ giga julọ ilẹ Naijiria kọ ẹbẹ ẹwọn Odun mẹwa ati awọn enia mẹjọ silẹ ni ọjọ kini Oṣu keje ọdun yi ti Ijọba tun gbe kuro l'ọgba ẹwọn Eko lọ si ọgba ẹwọn Kalaba ni ọjọ kẹsan Osu yi ni Iyawo rẹ ati Mama Iya afin Oloye H. I. D. Awolọwọ lọ ṣe abẹwo rẹ ni ọjọ'Bọ ti iṣe ọgbọnjọ oṣu keje ọdun yi.

Ninu awọn enia to tun ba iya afin, Oloye H. I. D. Awolọwọ ati iya rẹ lọ ṣe abẹwo olori ẹgbẹ Afẹnifẹre l'ọgba ẹwọn ni Kalaba ni ọmọge binrin k a n akọwe Oloye Awolọwọ ati Dirẹba to wa ọkọ Iya afin Oloye Awolọwọ ati Iya rẹ lọ si Kalaba lo pẹlu lọ ṣe abẹwo Oloye Awolọwọ.

Iya afin Ol ye Awolọwọ ati mama rẹ de si i l u Kalaba pẹlu awọn enia yoku ni dee d e agogo mọkania owurọ ni ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu keje ọdun yi, ṣugbọn ko si aye lati lọ ṣe abẹwo Oloye Awolọwọ ni ọjọ na Iya afin Awolọw pẹlu awọn enia rẹ lo si ile isimi fun awọn alejo lati lọ sun si ni ọ ọ na.

Nigbati di owurọ ọjọ keji ti iṣe ọgbọnjọ oṣu keje ọdun yi ni Iyaafin H. I. D Awo lọwọ ati iya rẹ pẹlu awọn enia yoku lọ si ọgba ẹwọn ilu Kalaba ni deede agogo mẹjọ owurọ ọjọ na ti nwọn si lọ ri Alakoso eto ọgba ẹwọn ilu Kalaba Ọgbẹni M A. Hijeh.

Lẹhin ti Iya afin, Oloye Awolọwọ ati awọn enia yoko lọ ri Alakoso eto ọgba ẹwọn ilu Kalaba ti nwọn si jijọ sọrọ fun nkan bi iṣẹju marun ni Iyaafin H I. D. Awolọwọ ati iya rẹ si



Iyaafin (Oloye) H. I. D. Awolọwọ

fi'iwe aye lati lọ ri Oloye Awolọwọ lati ọwọ A l a k o s o eto ọgba ẹwọn ilu Eko han Alakoso eto ọgba ẹwọn ti ilu Kalaba tan ni Iya afin Awolọwọ ati Iya rẹ pẹlu awọn enia yoku ti nwọn ba Iya-afin Oloye Awolọ ri olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oloye Awolọwọ ni ọgba ẹwọn ilu Kalaba ni anfani lati lọ ṣe ibẹwo Oloye Awolọwo

Awọn oniwe Irohin to ti gba labẹlẹ pe Iya afin Oloye H. I D. Awolọwọ ti de si ilu Kalaba ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọ j ọ kọkandinlọgbọn oṣu keje ọdun yi loti mura lati lọ si ọgba ẹwọn ilu Kalaba nibi ti Oloye Awolọwo ti nṣe ẹwọn ọdun mẹwa rẹ.

Oniwe irohin wa to wa ni ilu Kalaba fi ye wa ninu irohin rẹ pe gbiyanju lati le gbọ ti ohan fi Iya afin Oloye Awolọwọ ati iya rẹ ba oloye Awolọwọ sọrọ sugbọn awọn oniwe Irohin atl oniwe irohin wa Ejongboro ko ri aye rara lati le gbọ gbogbo ọrọ ti nwọn ba Oloye Awolọwọ sọ rara.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu irohin re pe on gbiyanju lati le ri Oloye iyaafin H I D Awolọwọ sọrọ sugbọn on ko ri iya afin Awoowọ rara ati Iya rẹ lati le fi ọrọ jomitoro



Oloye Awolọwọ

ọrọ lenu awọn enia meji na.

Nigbati oniwe irohin wa lọ ba akọwe Oloye Awolọwọ to ba iya Afin Awolọwọ wa latl Ibadan lọ si Kalaba lati le lọ se ibẹwo Oloye Awolọwọ to wa ni ọgba ẹwọn Kalaba lati le gbọ ọrọ lẹnu rẹ ati awọn nkan ti nwọn ba Oloye Awolọwọ sọ Akọwe Oloye Awolọwo fi ye oniwe Irohin wa pe nwọn ko le gbọ gb gbo ọrọ ti iya afin Oloyele Awolọwọ ati iya rẹ wa ba Oloye Awolọwọ sọ rara ati pe gbogbo ọrọ ti nwọn wa ba oloye Awolọwọ sọ patapata lo jẹ ọrọ aṣiri

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Kẹta)

Mo fi ọ jẹ oye Balogun loni, ilu fi ọ jẹ iya mi Oṣoronga, irinmalẹ ọkẹ ati tọdọ fi ọ jẹ, Ọlọrun papa fi ọ jẹ Ẹniti o ba nlepa rẹ lati ṣe ọ ni ibi yio sanku. Aki fi omi si ẹni fẹ ina o ṣewo. Gbogbo omi odo ati agbara ni fori f' Okun ohun ti o ba nṣe ko ni bi ọmọ araiye ninu gbogbo wọn ni aṣẹ.

**Lati Ọwọ J. O. SHOYINKA**

AYUNỌRUNBỌ PAPA BẸRẸSI SỌRỌ BI BALOGUN ILU.

Kabiyesi, Alayeluwa Alaṣẹ Ekeji Oriṣa, ki Ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ, mo dupẹ, mo tọpẹ da lọwọ gbogbo ilu fun Oye ti ẹ fi da mi lọla, Edumare yio tun ile ati ọna yin ṣe, a ko ni rogun gbamigbami Gẹgẹbi ẹ ti ṣe fi ọkan tan mi, nko ni ja yin kulẹ ẹ seun o.

Bayi ni awọn ilu ba Ayunorunbọ ko ritirit ajo yọ na lọ si ile rẹ.

Ọkan Ọba ko balẹ mọ hihilo da ba. O ro ikan ara rẹ pe, o pẹ ni, o ya ni, Ayunọrunbọ ni yio le on kuro lori oye, O fi ọrọ yi lọ awọn ẹmẹwa rẹ, ọrọ yi wa dati ẹniti o fi ọrọ lọ lọ ika, ẹmẹwa rẹ dahun o ni Kabiyesi mo ti fẹ sọ fun ọ ọjọ ti pẹ, pe ki o wa ọna lati yẹju Ayunọrunbọ bibẹkọ, on ni yio le ọ kuro lori oye, yio si fi ara rẹ jọba Ọba ni o s on, mo dupe, mo tọpẹ da o, ni kukuru Ọba ati awọn ẹmẹwa rẹ wa ẹsun si lẹsẹ nwọn pe wa si Afin nwọn ni lọjọ meje oni ki o fi ilu silẹ fun awọn, nwọn si tun sọ pe ko si alaye tabi ẹbẹ, ki o sa ṣe ohun ti awọn wi Ayunọrunbọ ko ṣe ori kunkun, ki o to to ọjọ keje o ti palẹ ẹru rẹ mọ, on ati awọn ẹbi rẹ ti mu ọna ajo wọn pọn, ṣugbọn ki o to ma lọ, o sọ gbo'ohun kan, Oni, Mo mọ daju pe ọtẹ ati ikorira ni ẹ fi nle mi lọ yi, ṣugbọn bi Ọlọrun ba nbẹ, ẹnyin gan ni ẹ o pe mi pada nitori pe nko ṣẹ yin nko si ro yin"

Nwọn bẹrẹ si yin mu si pe, sa ma lọ sa ma lọ a ko fẹ ọ ni ilu mọ, nigbati o ri pe awọn ọrẹ kori ko sun lọwọ ninu dulọmọ yi, o sọkun ki koro, o ni to aiye toto fun awọn iyawo rẹ ti salọ tan, iku awọn Ọmọ rẹ o fi ehin ti Oluọgan, o ni ki awọnỌmọ on so mọ on nidi, nwọn so mọ o fa onde kan yọ ninu apo, o fi na Oluọga o lanu hoo on ati awọn Ọmọ rẹ ko sinu Ọgan koro ọgan si pa ẹnu de, ha ṣe awọn ara ilu nitoripe O wọlẹ

Bayi ni nwọn wa nki Ọba ku ori re, Ọba Papa ṣe ase nla o si se sara pe on ri di ọta on Nigbati Panpalaso gbọ pe Ayunọrunbọ wọlẹ lo aye inu rẹ dun gidigidi o ni Ọlọrun muu,

Nigbati Ayunọrunbọ ṣẹ gun lẹẹ keji inu awọn ara Ilu Ori Eru dun pupọ lọjọ keji nwọn ko ara jọ o di ile Ayunọrunbọ gbogbo wọn bẹrẹ si dupẹ ohun ti o ṣe fun wọn Ayunọrunbọ Tẹnu Bọ Ọrọ Sisọ,

Ayunọrunbọ ki gbogbo awọn ara ilu fun wiwa fi wọn wa lati wa dupẹ ohun ti on ṣe O ni Ẹnyin Ọmọ iya mi lọkunrin lobinrin a ko le dupẹ ara ohun ti o ti kọja ti lọ ko tọ ko yẹ, lati tun ma ka ọran sun nyin lọjọ kini ẹ ditẹ mọ mi ẹ si le mi jade kuro larin ilu Ọba ati awọn ijoye lọwọ sii awọn si tẹsẹ si pẹlu mo lọ gẹgẹ bi Ọkunrin lọjọ na pẹlu awọn Ọmọ mi ọpọlọpọ ninu nyin nsọpe mo ti ri junu pẹlu awọn Ọmọ mi atipe **ẹranko** buburu si ti pa wa jẹ.

Lonii ẹ dupẹ lọwọ Ọlọrun, ẹ dupẹ lọwọ ori nyin ki e si dupẹ lọwọ aburo Baba Akessporo yale bi ki ba ṣe tirẹ ni, Ogun Panpalaṣo iba ko nyin raurau tọmọtọmọ ati ohun ọsin t'ohunọsin nisisiyi mo ja mọ ṣẹgun Nbo ni Ọba ati awọn Ijoye rẹ yio gba fun mi ?

Iyoku Dọunla.


## AFRICAN SPECIAL

- Full tropicalisation and underbody protection plates
- Strong and comfortable suspension.
- Outstanding road holding.
- Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
- HIGH RESALE VALUE.




LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.

# Barika Irohin Imọlẹ

Lati Ọwọ J. ỌLA. WINS

Adupẹ lọwọ Ọlọrun ti o ti iwe Irohin Imọlẹ lẹhin titi de ibiti o de loni yi, ọpẹ ni fun Ọlọrun ni oke-ọrun ati ni aiye alafia fun ibiti o ran wa lọwọ de; o di odidi ọdun kan gbako ti iwe Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ.

Awọn Yorubani o nma nkọrin kan pe, orire ni a ki ẹniti o lowo, orire ni a ki ẹniti o ba bimọ, orire ni ki ẹniti Ọlọrun ba dasi ẹmi ti o ṣe ọdun ti o kọja ti o tun ṣe eyi orire ni a ki, ẹ ku orire.

Mo ki gbogbo awọn oṣiṣẹ iwe Irohin Imọlẹ ku orire ati awọn ti nka lati esin wa pe, awọn na kuorire.

Nigbati iwe na kọkọ njade lojojumọ, ominu nkọ awọn ẹlomiran pe ,bawo ni ao ṣe ga ti ao fi mi gbun bayi? A si dupẹ lọwọ Ọlọrun ti ko fi wa silẹ ni iwaju kan. Lai fọta pe iṣẹ na nlọ daada pẹlu irọrun.

Nitootọ irin ọdun kan kiṣe ẹyọ, odidi ọsẹ mejileladọta ki ṣẹ wasa, iwe Irohin Imọlẹ ti la iṣoro ati wahala ja, gẹgẹbi ẹda, ẹgun ni lati wa lọna ṣugbon Ọluwa wa lẹhin rẹ o si yege ninu irin ọdun kan-

Oluwa ṣe nkan nla fun iwe Irohin Imọlẹ nitorina awa si nyọ, awa fi ọpẹ fun Oluwa nitori o ṣeun, anu Rẹ duro lailai.

O daju pe aiṇiye o o ni o ti nrọ ti de ilẹ si ti fi mu, ọpọpọlọ iwe miran ti jade lẹhin tiwa ti aiye si ti gbagbe rẹ pe o tilẹ jade ri, Omiran si ẹ ṣẹ kan ile ẹsẹ kan Ode.

Iṣẹ nla ti iwe Irohin Imọlẹ ti ṣe fun awọn ọmọ Yoruba o kọ yọyọ o si tun ka mimi kiṣe awọn ọmọ Yoruba nikan bi koṣe gbogbo awa ọmọ Naijiria Irohin ti o yẹ ki a ma gbọ diẹ ‹ ibẹ lọsosẹ ojo jumọ ni a nka ninu iwe na, bi a ba gbọ ọrọ ninu ẹrọ asọrọ magbesi ti ko ba ye wa bi a ba ti ni kọbọ meji lọwọ yekeyeke ni ao ka ni akaye ni ọjọ keji.

Eyiti ko ba ye wa ni ede Oyinbo Irohin Imọlẹ ni yio tumọ rẹ fun wa daada, ẹṣe Irohin Imọlẹ ti ṣe arin ọdun kan ti o di ojojumọ kọja nkan ti enia le fẹnu sọ a fi ẹniti o ba nka ni o le sọ adun to wa ninu rẹ.

Ko nbu enia, ko jẹ fi igba kan bọ ọkan ninu bi ọrọ ba tun ni o nsọ fun araiye wa.

Ọlọrun yio mọ wa pẹlu iwe Irohin Imọlẹ ko ni fi si lẹ nigba kan amin, mo tun ki gbogbo ẹnyin ti ẹ nsisẹ ninu iwe irohin Imọlẹ lati ọdọ Olori de ọdọ ọmọ ẹhin mo ki nyin ni ẹlẹmọsọ mo tun ki nyin tologun tologun, Ẹ ku iṣẹ o yio yẹ nyin o yiyẹ ni ni yẹ ẹiyẹle yio rọ nyin tirọ ni rọ adẹba l'ọrun, aṣẹ,

# YE IRAWỌ RE WO

AGUARIUS (Jan. 20-Feb, 18) Nwọn o mu irohin buburu kan wa fun ọ loni. Maṣe binu lojiji ki o ma ba ṣiwahu.

PISCES (Feb 19-March 20) Itẹlọrun wa fun ọ loni lẹnu iṣẹ ati ninu ile pẹlu.

ARIES (March 21- April 20) O gbọ irohin ijaiya kan loni ti ko ni jẹ ki opa ọkan pọ si oju kan. Maṣe sọ ireti nu.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni dara fun ọ lati lọ ṣe ibẹwo awọn ọrẹ rẹ. Ṣọra pẹlu owo olowo

GEMINI (May 21-June 21) Ọran owo kan wa niwaju t o mu inu rẹ dun loni, Ọjọ oni si tun dara fun ọ lati lọ si Oke Okun,

CANCER (June 22-July 22) Iṣẹ pupọ wa fun ọ lati ṣe loni ṣọra pẹlu iṣẹ aṣeju nitori aisan,

LEO (July 23–Aug 22) Ilọsiwaju wa fun ọ loni

VIRGO (Aug 23–Sept 22) Gbiyanju lati suomọ olufẹ rẹ daada loni maṣe jẹki okun ifẹ ti o wa larin yin o ja o,

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Idamu diẹ wa fun ọ loni ti ko ni fi ọkan rẹ balẹ,

SCORPIO (Oct 24 -Nov 22) O ṣe alabapade awọn enia kan ti o ṣe iranlọwọ fun ọ loni ti o ko ba kọ kan ti nwọn fẹ pe ọ si

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ilọsiwaju ati orire wa fun ọ loni, Maṣe lo asiko rẹ lori ohun ti o ko ṣe pe ipinnu le lori

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Gbiyanju lati ri awọn ti o nyanlodi ki o si ṣi iṣoro rẹ han wọn Nibẹ ni iranlọwọ wa fun ọ


BI O BA NI

1we—Titẹ

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi Iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyawo

KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE

Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos

EKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹkan soso ṣoṣo ko si ri Iyato



HELLO HELLO HELLO

OLUSHI SOCIALISTS

PRESENT

FIRST ANNIVERSARY DANCE

at Foresters Centenary Hall
22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p. m. till dawn

MUSIC BY

New Time Enterprises
Bashy & His Young Stars Orchestra

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band arom Ghana Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body fter clocing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSH NG

Bar Bar Inexhaustible

Tickets 3s Flat

Tickets obtainable at 16 Bamgbose Street, Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos

IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 759, SATURDAY, AUGUST 1, 1964 (2D)

## Ọba Olukarẹ Sọ pe Ki Awọn Oṣelu Ma Dahun Si Ọrọ Owo-Oṣu On Ti Nwọn Da Duro

IKARẸ:— Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kokanlelọgbọn oṣu yi ni Ọba Amusa Momoh kẹta, Olukarẹ ti ilu Ikarẹ ṣe ikilọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu pe ki ẹni kankan ma ṣe dasi ọrọ to wa larin on ati Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nipa ọrọ owo-oṣu on ti awọn Ijọba Ibilẹ ti ilu Ikarẹ sọ pe nwọn yio da duro fun oṣu mẹfa.

Ọba Amusa Momoh tun ṣe alaye ọrọ rẹ si awọn ẹgbẹ oṣelu ba ndahun si ọrọ nipa on tabi ki nwọn ma bu ẹnu ẹtẹ lu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria pe nṣe ni o tun mu ki ọrọ naburu si ni

Ọba Olukarẹ ti ilu Ikarẹ tun sọ siwaju si gbogbo ọrọ ti awọn ẹgbẹ oṣelu nsọ lori eru ti awọn igbimọ afunisho ti Ijọba ibilẹ ilu Ikare ṣe lori eto owo-osu on ti nwọn sọ pe awọn yio da duro fun odindi osu mẹfa gbako

Ọba Olukare rọ gbogbo awọn ẹgbẹ oselu na pe ki awọn ma ṣe ni owo ninu oro na rara ati lati le jẹki oro na le tete pari Ninu ọsẹ yi ni awon Ọba meji ni Ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria ngbinyanju lati le pari ija awon Ọba ti awon igbimo afunishọ kan nṣo pe nwon sọ owo-osu won di kobo kan ṣoṣo lodun ati papa fun ti owo-osu

Ọba Olukarẹ ti nwon tun sọ pe nwọn yio da duro fun odidi osu mẹfa.

# NWỌN FẸ YAN ỌBA ILESHA TITUN

IBADAN:— Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti yan awọn igbimọ Oloye mẹwa ti yio ṣe eto ẹniti yio jẹ Ọba Qwa ti ilu Ilesha ati pe ki awọn Igbimọ Oloye na tete ṣe eto to tọ ati eyi to yẹ lati le mọ ẹniti Ọba ilu Ilesha tọ si lati jẹ oye Ọba ilẹ Ijẹsha na.



OLOGBE ỌBA BILADU KEJI Qwa Ilu Ilesha

Irohin na de ọwọ wa lati inu iwe kan ti ile iṣẹ Alakoso eto awọn Oloye ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti ile iṣẹ ran ni si akọwe agba ti Ijọba Ibilẹ ilu Ilesha Oloye Adewusi.

Awọn Igbimọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yan lati ṣe eto ẹniti yio jẹ Ọba ilu Ilesha na ni awọn Oloye mẹwa lati ilu Ilesha ati awọn olori meje lati agbegbe ilu Ilesha to ṣe eto lori Oye jijẹ ni ẹkun Ijẹsha.

Awọn Oloye mẹwa ti yio ṣe eto ẹniti yio jẹ Oye Ọba na ni ilu Ilesha ni Ọbanla, Odole. Lẹjọka, Ogboni, Risawẹ, Loro, Ọbaodo, Saluro, Lejofi ati Ọrapatẹ.

Awọn Olori ilu agbegbe Ilesha ti yio pelu awọn Oloye mẹwa nii ilu Ilesha na ni awọn Olori ilu lati awọn ilu nwọnyi ni agbegbe Ilesha awọn ni:

Awọn Ọbọni lati ilu Ibokun, Ijẹbu-Jẹsha ati Ipolo, Lọja ti ilu Imesi ile ati Esa-Oke, ati Apetu ti ilu Ipetu Ijẹsha ati Oluwara ti ilu Ifẹ Wara. Awọn olori nwọnyi ni yio ṣe eto lati yan ẹniti yio jẹ Ọba titun fun ilu Ilesha.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ fun ilu Ilesha lo yẹ ki nwọn ṣe eto lati yan Ọba titun na ṣugbọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun si ti tun Igbimọ na ka dipo awọn Igbimọn na ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe fi awọn olori fun Igbimọ Ijọba ibilẹ fun agbegbe Ilesha rọpo wọn, lati le ṣe eto ẹniti yio jẹ Ọba titun na.

### IWE—ẸSUN

Nigbati ipo Ọba Qwa ti ilu Ilesha ṣomọ ninu oṣu keje ọdun to kọja ni Alakoso eto Oye jijẹ nigbana Oloye R. A. Akinyẹmi si fun Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu Ilesha lati ma ṣe eto awọn nkan to je pe Ọba Qwa ilu Ilesha lo yẹ ki o ma ṣe e

Nigbati awọn ara ilu Ilesha si bẹrẹ si kọ iwe ẹsun si Alakoso eto Oye jijẹ fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye R. A. Akinyẹmi pe eto oye Ọba Qwa ti ilu Ilesha pe ki iṣe fun gbogbo ara ilu Ilu Ilesha ni Oloye R. A. Akinyẹmi ṣe ileri lati ṣe eto nipa rẹ.

Lẹhin ti Alakoso eto oye jijẹ Ijọba ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti Oloye R.A. Akinyẹmi ti jẹ Alakoso eto Oye jijẹ si ṣe eto lati yan awọn igbimọ ti awọn Oloye ilu Ilesha lati ma ṣe eto ẹniti Ọba ilu Ilesha ba tọ si lati jẹ Ọba Qwa ti ilu Ilesha na,

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 1/8/64.